Akiyesi

Anfe Enti yio ma ba wa ta Iwe Irohin Imole. Ni agbegbe Ilorin tabi Ilumitan. E lo si odo Ogbeni:- A. O. AJIBOYE Esq Ni Oja Gambari Ilorin

# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.

AKIYESI

E ma polowo oja yin sinu Irohin Imole nigba gbogbo

VOL. III No 134 MONDAY JANUARY 25 — JANUARY 31 1960 KOBO KAN (1d)


## Ogbeni W. S. A. Warren so wipe Ofin to dara kise ohun ti enia nilati lodi si

Ogbeni W. S. A. Warren akowe Igbimo Ibile Ibadan fi imoran fun awon omo egbe igbimo pe ki won mase lodi si ofin ti o dara ti o si wulo.

Ogbeni Warren so oro yi nigbati o nba awon omo egbe igbimo soro ni ipade ososu ti won nse ni ile igbimo ni Mapo nihin, nigbati won soro lori oro ti omo egbe kan gbe wa si iwaju igbimo pe ki won mu ofin ti tito arin ilu Ibadan kuro. Lati enu Ogbeni Sanni ti omo Egbe Afenifere (Action Group) ni oro na ti jade, o si wipe ki Igbimo ba awon Alase Eto ilu soro lati ri wipe ki won ma fi owo kan ibugbe awon omo ibile Ibadan.

Nigbati a gbenu le oro yi Ogbeni Sanni bebe lati mu kuro ni siso, sugbon Alaga Igbimo Ogbeni A.M. F. Agbaje ko jale igbimo siso oro na won si fi ohun kan gba a. Igbimo tun gba pe ki a na metadilogun ole mewa egberun Poun fun ise omi ero ti Ibadan won tun gba pe ki a na egberunole ogorun merin Poun fun ilera ilu.

Nipa pe ki a na ogoji din legberun Poun fun ile ejo ibile, Igbimo gba pe ki awon omo egbe eto inawo to Igbimo lo daro na.

## Benson ni ejo lile lati je

Ogbeni V. E. Crane adajo agba ti ile ejo (Chief Magistrate) ti Eko so ni ojo Jimoh pe ejo lile gan ni esun ti a fi sun Ogbeni T. O. Shobowale Benson. Alase Eto Irohin ti Ijoba Apapo ile Naijiria.

O wa so pe ki Ogbeni Benson jejo ki o si se abo re lesekanna. Ogbeni Crane ko lati gba ebe agbejoro R. A. Fani-Kayode pe ki ile ejo yi ejo na si ojo miran lehin eyi ni Ogbeni Fani Kayode wa fi agbejoro miran Ogbeni J. A. Cole han adajo.

Ogbeni Cole tun wa bebe pe ki ile ejo gba pe ki a sun ejo na si ojo iwaju nitoripe agogo meji ti lu koja atipe ki aye le wa fun Ogbeni Benson lati se abo re nitoripe eni owo ni Ogbeni Benson je o de ye ki ile ejo da oro re wo.

Lesekanna ni Ogbeni C. K. J. Amachree Agbejoro Ijoba so wipe on ko gba o ni eleyi je ohun ti ko wa ara oro, iyen oro Ogbeni Cole, o wa se afinkun pe awon ti gbaye enia jankan to Adajo wa fi ejo na si oni

## Baba Omo merin ninu agbara eje

IBADAN. Awon ebi egbon, awon si nsokun kikoro nihin nigbati won ri Baba omo merin, ti o si je eni Ogoji odun ninu agbara eje ati ibon Sakabula ni egbere.

Ogbeni yi Johnson Idika, je Asode ni Ile Iwe giga ti Nigerian College of Arts Science and Technology, nihin.

Pelu ekun kikoro ati igbara ganle ni aya re fi so fun awon Olopa pe" ara oko on ko se were, lati bi ojo meta ki o to dipe nkan buruku yi sele, oko on ran on lo pe egbon re ni Oke Padre, nigbati on si ma pa da ni on ba ninu agbara eje.

A ti gbe oku re lo si ile

## P. A. Olagunju ku

Olukoni kan ni ile Eko giga ti University College Ibadan, ti a gbo pe o je omo odun mejidinlogbon, Dokita P. A. Olagunju ni o ku lesekanna, nigbati moto re ti on pelu omo ise re wa kolu igi kan ni ona Ibadan si Oshogbo.

Omo ise re ti won jijo wa ninu moto fi ara pa o si ni Ile itoju Alaisan ni Osho-

WO OJU EWE KERIN

Laku-laku, awon olopa si nse iwadi ohun ti o pa a.

Ninu iku ojiji, Oluwa re. re gba wa o. Amin.


## MOGBAYI BABY MIXTURE

OLURANLOWO FUN AWON ABIYAMO




MOGBAYI BABY MIXTURE je ogun pataki ta se ni Asepe fun Awon omode, ati nlo ogun yi fun opolopo odun sehin pelu idaniloju fun Awon ise ribiribi ti o ti nse. MOGBAYI BABY MIXTURE je egbogi to dara pupo fun igbona iko, otutu Aiperi, Osi imu omode, jedi jedi Kokoro ori omode. O dara fun omode ti ko tete rin ati fun awon aisan miran bebe lo. O nmu ki omode nia nsun fonfon, o nmu ki ehin sibu je iro fun fun awon omode, osi njeki awon omode lobi, osi nmu won dan ni awo. Enyin Abiyamo, eku afojuba egbogi yi. Aran yin leti pe MOGBAYI BABY MIXTURE je egbogi ti ko se mani fun awon omode. Ijafara lewu pupo, tete lo ra ti e ni ile itaja Egbogi towa ni Adugbo re.

Igo kekere re je 2/6d Igo nla je 4/6d
LILO RE:- Sibi kekere kan lemeta lojumo

*Wholesale Distributors*
A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHERS

6, Balogun Street West, Lagos Nigeria. Phone 22515

34, Docemo Street, Lagos. Phone 20424?

# Itan awon Omugo meta

NI igbakan, awọn ọkunrin mẹta jọ nṣe ore pọ. O r ẹ wọn na si pọ tobẹ ti ko si nkan ti yio de ni ọrọ asiri ti wọn ki sọ fun ara wọn.

Ni ọjọ kan, wọn ṣe ipade larin ara wọn pe o yẹ ki awọn mọ oyinbo diẹ sọ. Wọn ni nkan ti awọn yio ṣe ni wipe ki awọn lọ si ilewe ti ki yio gba awon ju oṣe kan lọ. larin o s ẹ kan yi o si ti yẹ ki awọn mọ ede oyinbo kokan sọ. Nigbati o ya, wọn b ẹ r ẹ ilewe, igbati yio fi to ọsẹ kan loto, won ti mọ oyinbo kokan sọ. Okan mọ We are the one, ekeji si mọ because of money sọ, ẹkẹta si mọ It serve us right sọ. Laijepe wọn mọ itumọ ọrọ wọnyi. Inu awọn mẹtẹta dun si ede oyinbo kokan ti awọn mọ yi.

Won jade ni ile ni ọjọ kan, gẹgẹbi mo ti sọ tẹlẹ pe wọn fi ara wọn s i l e, Won si rin irin ajo lọ silu kan, wọn rin titi wọn de arin aginju ni wọn ba oku ọkunrin onisowo kan nibẹ nigbati wọn ri oku yi aya wọn ja, ibiti wọn ti duro ti wọn nwo oku yi pẹlu ikanu ni Olopa gbe yọ si wọn. Nigbati ọlọpa de ibẹ ti owo oku ọkunrin onisowo yi ori ogbẹ kakiri ara rẹ, ọlọpa si bi awọn ọkunrin yi lere ni ede oyinbo pe tani paa? Ekini ko ti jẹ ko sọrọ dele oti sare dahun pe, We are the one" tii tumọ rẹ j ẹ " A-a ni', Olopa si tun bere ni ede oyinbo pe nitori kini wọn se paa? Ekeji si ti tun sare dahun pe', because of money" kaka ki wọn sọ pe awọn ko gbọ ede oyinbo ki Oloba sọrọ ni ede ti awọn gbọ. Won bẹrẹ si sọ isọkuso, inu Olopa osi fi ibinu sọ fun wọn pe ko si toyẹ wọn ju ki ẹpa wọn lọ Olopa simu wọn lọ ile ida jọ. Nigbati wọn de bẹ ọjọda ko ẹjọ oro funi Adajọ ati gbogbo wọn ṣe fun on lesi adajọ ni se wọn gba wipe awọn jẹbi iku. Were ni ẹkẹta ti dahun pe'' It serves us right eyi ti oje afaremo. Ni wọn ba yẹ igi fun awọn ọkunrin mẹta yi. Ni wọn ba ku iku aigbọn.

Nitori idi eyi mo bẹ gbogbo ẹnyin ọmọde ati agbalagba ati Okunrin ati Obinrin ki eye kọ ẹkọ abọ. Olorun yio ma sọ gbogbo wa.

Olotu modupẹ o, ọkọ ọba ko ni sa yin lẹsẹ Amin.

Lati ọwọ
Confort Titiloye Eaie

## IkoKo obe ni Kotu.

ENUGU. Koko ọbẹ ni wọn fi se ẹri ni ile ẹjọ, lẹhin ija iyawo meji ni idi aro. Awọn Ọlọpa sọ wipe awọn iyawo mejeji yi Ethel Nmuzo Nwizor iyawo alaru Railway ati Alice Etim iyawo olotu oko takisi ja ni idi aro lori ọrọ ale kan ti awọn mejeji yan. Ethel ninu ọrọ rẹ sọ wipe on mọ pe bibajẹ ni Alice mba on jẹ o iwaju akọwe U.A.C. kan nitori yan lale gẹgẹbi ti on. Oni ni igbati awọn nja ni idi aro ni Alice yi subu lu i k o k o ọbẹ ti o se. Awọn mejeji ni awọn ko jẹbi a i fi ẹjọ wọn si kọkan-dilọgbọn oṣu keji ọdun yi (29Febuary)nigbati a o tun gbe ikoko ọbẹ wa si ile ẹjọ.

## ILE AIYE

Olotu/ E jọwọ gbami laye diẹ lati fi ẹdun ọkan mi han nipa rogbodiyan ti o nṣẹlẹ kakiri agbaye.

Ekini ninu re nipa a gbọ lori ẹrọ redio pe nigbakugba lati oṣu yi lọ ni Faranse yio yin ẹtu oloro rẹ ni Sahara, atipe gbogbo ọkọ ogun ti Faranse yio wa daraya ninu okun wa ni Afrika ti lọwọ orun.

Elewọnyi fihan gbangba pe Faranse ko fẹ ọrẹ enie dudu rara atipe won nwa ona ati ma se idẹru ba wa, ki a ma le sọrọ ninu agbajọ aiye, ṣugbọn awa mọ pe ofo ni eleyi, agba ofifo ni o npariwo.

Ekeji kẹ ni ti ipade pẹ ti awọn alagbara aiye ti a lero pe wọn o se ni oṣu karun ọdun ni. Adura mi nipe ki o yanri si rere, nitori ti ko ba jẹ bẹ Alafia ile aiye le di ijefia. O yẹ o si tọ pe ki gbogbo wa fi si Adura pe ki Ọlọrun Oba wa tọ ile aiye yi ki alafia ati igbadun le wa ninu rẹ.

Emi ni ADEOLA ADENIYI



# MA FI OWURO S'ERE APA 2

Lati Owo: J. O. SHOYINKA Mushin)

Ojo pe, awon meteta fori le ile oba, ki won to wo afin, afin ti kun akunbe, awon enia nbo yanmu bi Yanmu-yanmu Oba papa ti joko lo ni isori-isori, won nreti awon meteta.

WON YO LOKOKAN AWON ONILU JU ILU SI

Bi won ti yo tien lokokan ni awon Onilu ju ilu si, won nlu lu yi pe.

Won de, Sinsindadasin,
Won de, Awon Eranko a buje bu da nu won de
Awon Elegiri won de.

Nigbati awon Ilu ati Oba ti gbo bayi gbogbo won si wa ni idakeje.

Ni kukuru awon meteta wole, won si lo yile niwaju oba, Oba papa si ki won dada, lehinna ni oba dide ganboro, o fi awon meteta han awon Ilu, o ni laise aniani gbogbo nyin e ti ngburo awon Okunrin won yin, opolopo ni o si ti mo won dajudaju.

Ohun ti o mu ni pe won wa siwaju nyin loni ni pe ti ko ba ni idi pataki obinrin ki je "KUMOLU" oruko ti awon meteta si nje ni idi pataki, mo si ripe o to, si ye ki emi Oba ilu le mo itumo oruko meteta, ki enikokan ninu won si se alaye kikun awon ilu Damuso, nipe Kabiyesi o wi re o, o wi re o, awa papa fe mo itumo oruko awon jagunlabi yi.

Mafaro Sere lo koko dide san ninu Ilu ati Oba, o ni, Kabiyesi o, Alaiyeluwa Alase ekeji Orisa ki ade pe lori ki bata ko pe lese, eni ti o ba gbogun ti o, ogun na ni yio pa, eni to ba ni ki tire ma dara, inu ise ni yio ku si, gbogbo ilu ni ase.

Mo si tun ki enyin ilu ti e pejo lati wa gbo itumo oruko wa, bayi bayi ni ki a ma ri, e ko ni gbe omo sin laise ibi, gbogbo won ni ase.

Awon meteta ti e ri yi, ti otito o o ba de ile ki a so, a ko ni iya, a ko ni baba, ajule orun ni awa mejeji ti pade ara wa, wiwo ni a si wo bo lati oju orun eyi fi han nyin daju daju pe orun ni ati wo bo bi yinyin, ko si si Opitan kinda duro be na, Adeda lo ran wa wa si ile aiye. Isti wa fi iriri ti a ri ko awon enia aiye logbon, ki olukuluku ba le ma mo atina lo ise re ni ile aiye.

E jowo e mase sope oro mi po pupoju, won nje bi owe, bi owe, ni anlu ilu AGIDIGBO eniti o ba mo ni o njaa. Gbogbo oro yoku ti mo fe ba nyin, itan ni ngo fi paa.

Akiyesi:- Eyi ni lati fi kede fun enyin oluka itan mi pe, itan mi ma kun ju bayi lo, sugbon ko si aye ninu Iwe Irohin Imole to be; ki se ejo mi o, ti e ba nife ni kikun gegebi e ti nkowe si mi nigbagbogbo, e le fi eyi si etigbo Olotu Ogbeni E. A. Adeniji 16, Bamgbose St Lagos on lo ni agbara lati se eto yi ni kikun.

Iwo lati kowe fun Calendar 1960 ati Asiri Iwase ti awon agbalagba fi nse agbara LOFE b ? Te'e fi 2d Stam ranse si wa fun gbigbe pada.

J. O. Shoyinka 6, Ojo Road, Oduabore Mushin

## Otelemuyen nki nyin o!

EKU LAILAI, e ma ku atijo. Oju to ri nyin gbo keke bi obi.

Mo ti mo daju-daju pe opolopo ninu nyin ni yio ti ma bere pe nibo ni Otelemuyen wole si.? atile ti ghuro re o to ojo meta —

Emi Otelemuyen ko ku, beni nko si run,, sugbon ona ni ko gba ibi kan lo, Mo ti mo daju pe inu enyin Oluse-buburu yio ma dun nisisiyi pe Otelemuyen ti nu lo dehun-dehun ko si eniti yio tun da wa ni idagiri mo.

He! ya Okunrin tun de Ori ki fo Awun, edo ki si dun igbin otutu ki si, mu eja ni ale odo. Ibiti e ba ri ki e kigbe mi lo. Ohun pataki ti mo tun fi be sode lojiji, ni lati fi ki Olotu Irohin Imole re mo ngbadun Iwe ti o nte jade ninu odun yi, o han, o ri reke-te.

Odua yio ma jeki owo re roke o, ko ni mo ise ni ile aiye ti a wa yi, emi Otele-muyen papa ko ni mo o. Ase.

Lose to mbo, lagbara Odua, mo te kolu awon OBINRIN ti o nda BONSUE" si owo, ngo laali won, ti nwon ko ni to ra ni epinni — Odigba o.!

## Olagunju

O BERE LATI OJU EWE KINI

gbo.

Dokita Olagunju ka'we ni Ile-Iwe giga ti Oxford ni Ilu Geesi, ni odun tokoja lo si ka'we re tan ki o to wa pada si Naijiria. O si bere Ise ni ile Eko giga ti University College Ibadan.

Ninu iku ojiji, Oluwa re re gba wa nibe. Amin.




Fi owo ati Stamp 1/- ranse si J. O. SHOYINK 6, Ojo Road (Oduabore) Mushin

## Egbogi fun tita ati Iwosan Orisirisi

(1) A nse orisirisi oju owo Egogi loke pelesi yi fun tita ati fun Itoju orisirisi Aisan tabi Amodi (2) A nse Itoju obinrin titi won yio fi loyun D. V. (3) A nse Itoju aboyun titi won yio fi bimo D. V. (4) A nse Itoju Obinrin ti nkan osu se mo lara (5) A nse Ajo fun t'okunrin t'obinrin ki won leri ise se. (6) A nse Ajo fun obinrin kio le ri oko fe. (7) A nse Ajo Okunrin ki o le ri aya fe. (8) A nse Ajo fun onisowo ki won le ma ri oja ta, ati ki won le ma ta daradara (9) A nse Ajo ki irepo wa larin t'oko t'aya. (10) A nse Ajo ki arati se le baci kale san gbese tabi je (11) A nse Ajo fun isegun lori nkan ajjodu tabi ota ati Ejo Court. (12) A nse Ajo oju dehin (13) A nse Ajo fun Adakole pelu imarale Aleko okonrin (14) A nse Ajo fun Eyonu, Aiye Enpou awon iya wa (15) A nse Ink fun Iko Petition (16) A nse egbogi isoye ati oomo kale Bori tabi (Fasei orisirisi Idanwo (Examination)

17. Ipara Aroki, Lojumo (fun faja faja, oun nle Alajonu huburu kuro eile) Cigarette Cup or Pkt. 10/- 5/- 2/6

J. B. Crownson Odujobi & Sons.
Top Floor. 16, Bamgbose Street, Lagos.

Printed and Published by MODUPE PRINTING PRESS 16, Bamgbose Street, Lagos Phone: 21986. Olotu E.A. Adeniji 51 Tejuosho Street Surulere YABA

FUN OWO "IROHIN IMOLE" ODUN KAN EKO— Sile Metin ati Kobo Metin (4/4d) ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun, Sile Mefa ati Kobo Mefa 6/6d)